# IWE KINNI

TI

# AWỌN AKEWI.

(*YORUBA PHILOSOPHY.*)

NIPA

DENRELE ADETIMKAN ỌBASA,
*Editor of The "Yoruba News," Ibadan.*

PUBLISHED BY
EGBE AGBA-'O-TAN.

*All Rights Reserved.*

PRINTED AT
THE ILARE PRESS, IBADAN

# IJUBA.

Mo juba o:—

Pẹlu ọ̀wọ̀ ni mo fi ran Iwe Kinni ti "Awọn Akewi" yi jade, mo si ni ireti pe ẹ o tẹwọgba diẹ yi na pẹlu inudidun.

O di ọdun mọkanlelogbon nisisiyi (A D 1896) ti mo ti bẹrẹ si ṣāyan kikojọ awọn ọrọ ọgbọn ataiye-baiye ti awọn baba nla wa, ti i mā han jade ninu orin ègè, rárà iyàá ìpẹ̀sà arofọ, oriki, ilu, fèrè ati agbeka ọrọ wọn: pupọ ninu wọn li o farajọ ti awọn arofọ awọn ọjọgbọn ti ilu oibo ti a nkọ ni ni awọn ile-ẹkọ wa: gẹgẹ bi "Homer," Longfellow," 'Shake-speare" ati awọn mi bẹbẹ lọ. O si danilọju pe kikọ ti wọn kọ nwọn silẹ ni a fi nle ranti awọn ọrọ iye-biye wọnni, ati pe, ko si ohun ti o yẹ wa bi orilẹ-ede bi pe ki a kọ tiwa nā silẹ fun anfani awọn enia wa ati ti iran ti mbọ.

Bi o si tijẹ pe "A ki i mọ iwe k a k aiye ja" inu mi yio dun lati ri imọran gba lọdọ enyin baba, ẹgbọn, ọrẹ ati ojulumọ wa gbogbo nipa ọna ti iwe yi tosi fun atunṣe, afikun tabi atunto ti o yẹ, ki a to tun tẹ awọn Ọwọ Keji

Emi ni ti nyin fun lilẹ wa

D. A. ỌBAṢA

Orile Ilarẹ,

Ibadan, 12th February 1927.